# FIFI ARA ẸNI RUBỌ FUN JESU

## Matteu 16:24-27;Luku 14:33; Filippi 3:8; Romu 15:1-3

## ẸKỌ 469 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nitori Kristi pẹlu kò ṣe ohun ti o wù ara rẹ" (Romu 15:3).**

**Isin Ifẹ**

Ninu Bibeli a kà nipa ọ̀pọlọpọ awọn eniyan ti wọn ṣe ifararubọ nlá nlà ki wọn ba le sin Oluwa. Wọn "du" ara wọn ni igbadun ati irọrun pupọ nitori wọn fẹ Ọlọrun, wọn si fẹ wu U. Awọn ẹsin miiran n fẹ ki awọn ọmọ-ẹyin wọn fasẹyin kuro ni jijẹ awọn ounjẹ kan, awọn eniyan si rò pe wọn le wu Ọlọrun lọna bayii, ṣugbọn inu Oluwa kò dùn si awọn iru iṣe bawọnni. Eniyan kò le gba ojurere Ọlọrun nipa ṣiṣe bẹẹ, tabi ki o mu Ọlọrun fun un ni ere nla paapaa fun jijẹ ara rẹ niya.

**Isin Eke**

Ni ọdun diẹ sẹyin nigba ti Ajihinrere wa wà ni Mexico, o ṣe akiyesi awọn obinrin alaini ati alaisan ara India ti wọn n rin kọja lori eekun wọn loju ọna ti a fi okuta ṣakuṣaku ṣe bi wọn ti n sun mọ ile oriṣa Wundia Guadeloupe. Wọn ni ireti lati ri ojurere Wundia yii, ki o si wo wọn sàn kuro ninu ipọnju wọn, ṣugbọn kò ràn wọ́n lọwọ rara.

A kà nipa awọn keferi ni ilẹ okeere ti wọn ti sọ awọn ọmọ-ọwọ wọn paapaa sinu Odo Nile fun ọni lati jẹ, ki wọn ba le ri ojurere awọn oriṣa ti kò tilẹ sí rara. Ṣugbọn gbogbo awọn nnkan wọnyii ni o buru loju Ọlọrun otitọ́ kan ṣoṣo. O wo awọn iru eniyan bẹẹ lati oke wá, O si gbiyanju lati fi hàn wọn pe Oun fẹ ki wọn sin Oun ni ẹmi ati otitọ, lati inu ọkàn wá.

**Isẹra-Ẹni**

Nigba miiran a n gbọ́ ti wọn wi pe ifẹ kò ni oṣuwọn ninu isin ọmọlẹyin rẹ. Bawo ni eyi ti jẹ otitọ to! O rọrùn fun ìyá lati ji ni oru nigba ti ọmọ-ọwọ rẹ ba n ké, kiakia ni yoo si dide lati tọju rẹ; ni gbogbo ọjọ ni iya fi n ṣiṣẹ lati se ounjẹ fun ọkọ rẹ ati awọn ọmọ rẹ; awọn ibusun wà lati tọju, ilẹ wa lati gbá, aṣọ wà lati fọ̀ ati lati lọ̀, ounjẹ wà lati fi pamọ sinu paanu. Baba maa n tete dide lowurọ, lati ṣiṣẹ ni gbogbo ọjọ, lai ka ojo tabi oorun si. Ọpọlọpọ awọn obi ni wọn fẹran awọn ọmọ wọn, ti wọn si n ṣe awọn ojuṣe wọn si wọn lai si aroye.

Ọkunrin ati obinrin, ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin ti a ti gbala ti fi ọkàn ati ayé wọn fun Jesu. Ni tootọ, wọn ni iṣẹ ti wọn ni ile, ni ibi iṣẹ tabi ni ile-ẹkọ. Ṣugbọn wọn ni lati ṣaapọn ninu awọn ohun ti Oluwa ju awọn ohun igba isisiyii lọ. Wọn gbọdọ ni ifẹ lati pa awọn aapọn ti kò yẹ tì si apa kan ki wọn ba le wu Oluwa ati ki wọn ba le ni akoko si i fun iṣẹ Oluwa.

Paulu kọwe si awọn ará Romu, o si sọ fun wọn pe awọn ti o lera nipa ti ẹmi gbọdọ ru awọn alailera -- awọn ti a ṣẹṣẹ gbala tabi awọn Onigbagbọ ti kò duro deedee; o wi pe awọn eniyan kò gbọdọ gbiyanju lati tẹ́ ara wọn lọrun, nitori "Kristi pẹlu kò ṣe ohun ti o wù ara rẹ."

Jesu wi pe: "Bi ẹnikan ba nfẹ lati tọ̀ mi lẹhin, ki o sẹ ara rẹ, ki o si gbé agbelebu rẹ, ki o si mã tọ̀ mi lẹhin. Nitori ẹnikẹni ti o ba fẹ gbà ẹmi rẹ là, yio sọ ọ nù: ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba sọ ẹmi rẹ nù nitori mi, yio ri i." Ẹ jẹ ki a kọ́ ohun ti o jẹ́ lati sẹ́ ara wa, ki a gbé agbelebu wa ki a si tẹle Jesu. Igbesi-ayé ti ode-oni, ni oniruuru igbadun ati aapọn nlá nlà ti o le gba akoko eniyan lati igba ti o ti ji lowurọ kutu titi di akoko ti o fẹ lọ sùn lalẹ. Diẹ ninu awọn nnkan wọnyii le ṣai mu ẹ̀ṣẹ lọwọ, ṣugbọn nigba ti a mọ̀ pe akoko kuru, Jesu si le de ni igbakigba, a mọ̀ pe akoko gan an ni yii fun olukuluku Onigbagbọ́ lati kún fun iṣẹ Oluwa. Nigba pupọ ni a maa n ri ọrọ akọle yii: "Igbesi-ayé kan peré ni a ni igbé, yoo si kọja lọ lai pe; nnkan ti a ba ṣe fun Kristi nikan ni yoo wà pẹ́."

**Awọn Apẹẹrẹ Iwa-bi-Ọlọrun**

Ẹ jẹ ki a kọ́ ẹkọ nipa igbesi-ayé diẹ ninu awọn eniyan Ọlọrun ti wọn ṣe ifararubọ, ti wọn si gbé igbesi-ayé isẹra-ẹni, ti wọn wu Ọlọrun lai ka ifẹ inu ara wọn si. Paulu jẹ́ ọ̀kan ninu awọn wọnni ti wọn "fi ẹmí wọn (lelẹ tabi) wewu nitori orukọ Oluwa wa Jesu Kristi" (Iṣe Awọn Apọsteli 15:26). Kò ka ẹmi rẹ si nnkan ti o ṣọwọn fun un, ṣugbọn o fi gbogbo rẹ silẹ fun Jesu. Paulu sọ nipa bi a ti fi ọgọ lu u, ti a sọ ọ ni okuta, ti ọkọ̀ rì i, ti ole si ja a; o jiya irora, aarẹ, ebi, oungbẹ, otutu ati ihoho. O gbé ẹrù awọn eniyan Ọlọrun le ọkàn rẹ pẹlu, o gbaawẹ,

o si gbadura fun wọn. O fi tayọtayọ wi pe oun yoo ná owo, ná ara fun awọn ọmọ Ọlọrun, oun si ti kọ́ lati ni itẹlọrun, boya oun ni diẹ tabi pupọ.

Dafidi pẹlu, fi awọn ohun pupọ du ara rẹ̀ ki o ba le wu Ọlọrun. Ni igba kan nigba ti o ja ogun kan pari, nigba ti oungbẹ gbẹ ẹ rekọja, meji ninu ọmọ-ogun fi ẹmi wọn wewu lati mu omi wá fun Dafidi, ṣugbọn nigba ti wọn mu un wá fun Dafidi, o wi pe oun ko le mu un, nitori awọn eniyan naa ti fi ẹmi wọn wewu lati mu omi naa wá, oun si tú omi naa silẹ gẹgẹ bi ẹbọ fun Oluwa.

Mose kọ awọn iṣura Egipti, "o kuku yàn lati mã bá awọn enia Ọlọrun jìya, jù ati jẹ fãji ẹ̀ṣẹ fun igba diẹ" (Heberu 11:25).

Abrahamu jẹ́ ẹlomiran ninu awọn akọni ninu igbagbọ́, ti o gbé igbesi-ayé isẹra-ẹni, o n gbé inu agọ, gẹgẹ bi alejo ati atipo lori ilẹ ayé, "nitoriti o nreti ilu ti o ni ipilẹ, eyiti Ọlọrun tẹ̀do ti o si kọ́" (Heberu 11:10). Nigba ti idanwo ti o ga jù lọ dé, Abrahamu kò jafara lati gbọran si Ọlọrun, o si fi ọmọ rẹ̀ kan ṣoṣo, Isaaki rubọ. Abrahamu gbagbọ́ pe Ọlọrun tilẹ le ji i dide paapaa kuro ninu oku. Nigba ti Abrahamu gbé ọbẹ rẹ̀ soke lati pa ọmọ rẹ̀, angẹli Oluwa dá a duro o si sọ fun un pe ki o má ṣe ṣe bẹẹ, nitori nisisiyii Ọlọrun mọ̀ pe Abrahamu bẹru Oun, o si fẹran Oun. Agbò kan ti o fi iwo rẹ̀ há ninu pantiri wà nibẹ. Abrahamu si fi rubọ sisun dipo ọmọ rẹ̀.

**Isin Lati Inu Ọkàn**

Awọn wọnyii ati ọpọlọpọ awọn miiran ninu Ọrọ Ọlọrun jẹ apẹẹrẹ ifara-ẹni-rubọ, iyara-ẹni-sọtọ ati isẹra-ẹni. Lode oni, Oluwa kò beere iru awọn ifararubọ ti ode ara nlá nlà bẹẹ, boya; ṣugbọn ọkàn wa ni Oun n fẹ. Njẹ a n fẹ fi awọn ohun kékèké paapaa du ara wa fun Un, ẹni ti o fun wa ni ohun gbogbo? Ẹ jẹ ki a yẹ ara wa wò.

Jesu wi pe, ẹnikẹni ti ko ba kọ̀ ohun gbogbo ti o ni, ko le ṣe ọmọ-ẹyin Oun. Eyi ki i ṣe pe ki a rin kuro ninu ile ṣugbọn itumọ rẹ̀ ni pe ki a fi ọwọ dẹngbẹrẹ mú ohun gbogbo ti Ọlọrun ti fi fun wa, ki a si mura tán lati fi ohunkohun ti Oluwa ba beere lọwọ wa silẹ. O le wi fun wa pe ki a lọ bẹ alaisan wò, tabi ki a kọ́ ohun-elo orin ki a le maa ba wọn fi ohun-elo orin yin Ọlọrun logo ninu Ile Ọlọrun; O le fẹ ki a fi owó wa silẹ fun iṣẹ itankalẹ Ihinrere. O le fi ẹni kan ti o fẹ iranwọ hàn wá, tabi O le fẹ ki a lo akoko pupọ si i fun adura gbigbà ati Bibeli kíkà.

A le padanu diẹ ninu anfaani nini awọn ohun ayé, ṣugbọn eyi ki i ṣe ohun pataki. A le maa wo awọn ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin miiran ti wọn dabi ẹni ti o lowo pupọ lati ná lori faaji ati aṣọ. Ki ni yoo jẹ bi a ba sọ diẹ ninu awọn nnkan ayé nù, ohun ti o ṣe pataki ju lọ ni lati gbọran si ohùn Olugbala wa, ki a mura silẹ lati pade Jesu nigba ti o ba de, ki a si ran awọn ẹlomiran lọwọ lati wá sọdọ Jesu pẹlu.

A n ṣe odiwọn ifẹ wa si Ọlọrun nipa igbọran wa si I ati isin atọkanwa ti a fun Un. Ẹ jẹ ki a beere lọwọ ara wa boya a fẹran Rẹ̀ to bẹẹ gẹẹ ti a le sẹ́ ara wa ki a si ṣe awọn ifararubọ ki a ba le sin In lọna ti o dara ju bẹẹ lọ. Bi a ba ni ifẹ ti o pé ati oore-ọfẹ Ọlọrun ninu ọkàn wa, a o fi tifẹtifẹ ati tayọtayọ ṣe ohunkohun ti O bá beere lọwọ wa.

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni itumọ isẹra-ẹni?
2. Darukọ diẹ ninu awọn nnkan ti a le fi silẹ fun Jesu.
3. Sọ apẹẹrẹ awọn eniyan mẹta ti wọn ṣe ifararubọ nla fun Oluwa.
4. Ki ni èrè awọn oloootọ Onigbagbọ́ ti wọn gbé igbesi-ayé isẹra-ẹni?
5. Njẹ ẹnikẹni le ri oju rere Ọlọrun nipa jijẹ ara rẹ̀ niyà?
6. Ki ni a le ṣe lati ni ibukun Ọlọrun lori wa?
7. Ki ni n mu Onigbagbọ́ ṣiṣẹ́ fun Jesu?
8. Njẹ ohun iṣoro ni fun Onigbagbọ́ lati gbọran si Jesu?
9. Iru isin wo ni Onigbagbọ́ tootọ n fun Ọlọrun?